# AWỌN ILÉ-IWE IJỌBA TI AGBEGBE BALTIMORE
# OWÓ'YÁ IRIN-IṢẸ́ AKẸ́KỌ̀Ọ́ ATI AJỌSỌ FUN LÍLO

## IFITONILETI

| | | |
|---|---|---|
| Ẹkunrẹrẹ Orukọ Akẹkọọ: | Ẹkunrẹrẹ Orukọ Obi/Alagbatọ́: | |
| S Ile-iwe: | Imeeli Obí/Alágbatọ́: | |
| Ipele Akẹ́kọ̀ọ́: | Nọmba Idánimọ Akẹ́kọ̀ọ́: | Ọdún Ikẹ́kọ̀ọ́: |
| Foonu Ilé Obí: | Foonu Ibi Iṣẹ́: | Foonu Alágbeéká: |

## IFITÓNILÉTI IRINṢẸ̀ALAALAYÉ NIPA IRIN-IṢẸA

Jọwọ́ wo gbogbo eyi tí ó bá a mu nísalẹ yii.

| | | |
|---|---|---|
| ☐ Irin-iṣẹ́ | ☐ Àpò Irin-Iṣẹ́ | ☐ Ẹrọ Ìdámọ Àtagbà Alágbeeká |
| ☐ Gbohungbohun etí | ☐ Okùn Iná | ☐ Omíràn |

## AJỌSỌ ILÒ OBÍ/ALAGBATỌ

1. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé ilo irin-iṣẹ́ naa dá lórí Ofin Ajọ Ẹkọ́ 6202 ati Ilana Iṣakóso 6202, pẹlú *Ofin Ti O Faye Gba Ilo Imọ-Ẹrọ (TAUP) fun Awọn Akẹ́kọ̀ọ́*.

2. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, gba á bi iṣẹ́ lati mu irin-iṣẹ́ ti ó ti níná lára ati awọn iṣọngbe rẹ wá si ilé-iwé ni gbogbo ọjọ ilé-iwé lati lo ninú awọn kilaasi ti a bá yan mí sí.

3. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé mo ní ojúṣe fún iwa mi nígbà ti mo bá nlo awọn ẹrọ alátagbà ati imọ-ẹrọ awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore.

4. Awa, ati ọmọ ati obí loye pé irin-iṣẹ́ naa ati awọn ìṣọ̀ngbè rẹ̀ jẹ́ dúkìá awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore tí a sì lérò láti lòó fún ètò ẹ̀kọ́ nìkan. Irin-iṣẹ naa wa fún ilo akẹ́kọ̀ọ́ ti a yàn a fún nìkan. O yé wa pé a ó sanwó fún irin-iṣẹ́ ati awọn ìṣọ̀ngbè ti a ko bá dá pada.

5. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé ìlò irin-iṣẹ naa fun eto ẹ̀kọ́ nikan lè wáyé ní ìta ilé-ìwé. Ṣugbọ́n, o yé mi pé nṣe ni a gbọ́dọ̀ lò irin-iṣẹ naa lati ṣe atilẹyin iṣẹ́ ìkẹ́kọ̀ọ́ àtiléwá, àkànṣe iṣẹ́, abi iṣẹ́ ìwádìí ti ilé-ìwé yan fúnni.

6. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, ní ojúṣe, ni gbogbo ìgbà, fún ìtọ́jú àti ìlò daradara irin-iṣẹ́ naa. Ti irin-iṣẹ́ naa ba sọnù abí wọ́n jíi lọ, Maa: (1) fi iròyin irin-iṣe ti o sọnu naa tó ọga ile-ìwé mi leti laarin ọjọ́ méji; (2) tèlé awọn ilana ifitonileti ilé-ìwé; àti (3) fọwọ́ sowọ́pọ̀ ní kíkún pẹlú ètò iwádìí.

7. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé iye owó tí ó ba yọju nipasẹ̀ bibà nnkan jẹ́ tí ó yọrí sí ìbàjẹ́ ìmọ̀-èrọ awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore abí awọn irin-iṣẹ ti awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore fúnni yoo jẹ́ ojuṣe akẹ́kọ̀ọ́ ti kò ṣe ojúṣe rẹ abi ti ó fà á, fún àpẹẹrẹ yíyọ àlẹ̀mọ́ kúrò, yíyọ kọ́kọ́rọ́ kúrò, ati bẹẹ bẹẹ lọ.

8. I Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, ó yé mi pé ojuṣe mi ni lati daabò bò irin-iṣẹ naa ni gbogbo igbà, ati lati fi apò rè gbé e kiri. Ó yé mi pe mi o ní fi irin-iṣẹ naa sílẹ̀ abi ni ọna miran fi i pamọ́ sinú ọkọ̀ nibi ti ooru ti o pọ̀ ti lè bà àwọn ẹ̀yà/abala rẹ̀ jẹ́.

9. Èmi, gẹgẹ bi òbí, lóye pé ojúṣe emi nikan ni lati bojuto bí ọmọ mi ti nlò ẹro aye-lu-jára nígbà tí o bá wọnú ẹ̀rọ alátagba awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore lati ilé abi ojuko ti kii ṣe ilẹ-iwe.

10. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé lilo irinṣẹ́ naa fun ere ara ẹni abí okowo tó lére, ríṛoni fun ete yoowu, awọn iṣẹ́ ọrọ ajé, awọn ohun tí ko bófin mu, lati wọlé sínú abí gbé alaye ara ẹni sórí ẹrọ awujọ abi awọn ojú ila ori ẹrọ miran ni a fi ofin de.

11. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, ní ojúṣe fún idáàbòbò ẹ̀rọ alátagbà awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore. Mi ò níí gbìyànjú láti fori ìlànà aabo abí awọn asẹ́ ẹrọ aye-lu-jara, abi ti ọwọ bọ iṣẹ́ ṣiṣe ẹrọ alátagba nípa fífi si abí gbígba awọn sọfwea, eré idáraya, prograamu, faili, ẹrọ iroyin, awọn nnkan adá-nikan-gba ori ẹrọ, abí láti awọn ọna míran. Maa jiyin fún dídáabo bo dukiá ilé-iwé. Ó yé mi pé ofin de biba nnkan jẹ́. Lara eyi ni, ṣugbọ́n ti kò pin sí wíwọlé sínú, yíyí padà, abi bíba jẹ́ ohun elo, awọn prograamu, faili, àbi àwọn ìlànà orí ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá abí orisun ìmọ̀-ẹ̀rọ. Ó yé mi pé mo nílò láti gbà àṣẹ lati ọdọ oludari ile-iwe abí olùkọ́ lati lò awọn fánrán lorí irin-iṣẹ́ naa.

12. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé a fún mi ni irin-iṣẹ́ naa ní ọdún ìkẹ́kọ̀ọ́ tí a wà yìí. Mo gbà lati jọ̀wọ́ irin-iṣẹ naa ati gbogbo awọn ìṣọ̀ngbè tí a yàn pẹ̀lú rẹ̀ fún ọ̀gá ilé-ìwé mi àbí ẹni ti ó yàn: (1) lẹyin ọdun ikẹkọọ; (2) ti mo bá ṣipò pada lọ si ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore miran; abi (3) yọwọ́ ninu eto abi ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore kan. Ó yé mi pe emi ni yoo fara mọ irinṣẹ abi awọn ìṣọ̀ngbè ti a ko ba da pada.

13. Mo gba láti tẹlé àwọn ìlanà atilẹyin ati àtúnṣe irin-iṣẹ ti ilé-ìwé gbé kalẹ kí nsì ṣe ifitonileti ibajẹ́ lọ́gán.

14. O yé mi pé ilé-ìwé lè gba àwọn irin-iṣẹ́ fún àyẹ̀wò, àtúnṣe, pẹ̀lú/abi atunṣe atigba-dégbà nígbakigbà abi fun idi yoowu.

15. Emi, gẹgẹ bi akẹ́kọ̀ọ́, lóye pé lílò irin-iṣẹ naa ni ọna yoowu laigba aṣẹ lè yọri sí ipadanu awọn anfaani irin-iṣe naa abi ifiyajẹni.

16. Awa, ati akẹ́kọ̀ọ́ ati obí, lóye pe kii ṣe ojúṣe awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore láti san gbese ti a ko gbàṣẹ nipa rẹ ti akẹkọọ ti o nlo awọn imọ-ẹrọ awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore ti ọrun bọ.

17. Awa, ati akẹ́kọ̀ọ ati obí lóye pe kii ṣe ojuṣe awọn ile-iwe ijọba ti agbegbè Baltimore ti ifitonileti yoowu bá sọnu, bajẹ, abi ti a ko rii latari ẹrọ ti ko ṣiṣẹ daradara abi awọn iṣoro míràn.

## AJỌSỌ AKẸKỌỌ

Mo ti ṣe agbeyẹwo *Ofin Ajọ Ẹkọ́ 6202 ati Ilana Iṣakóso 6202, Ofin Ti O Faye Gba Ilo Imọ-Ẹrọ (TAUP) fun Awọn Akẹ́kọ̀ọ́*, ti mo si gbà lati tẹlé gbogbo ojúṣe ti a là kalẹ̀ lókè yii.

| | |
|---|---|
| Ibọwọlu Akẹkọọ: | Deeti: |

## IFỌWỌSI OBI

Mo fi ọwọ́ sii pe emi ni òbí/alágbàtọ́ lábẹ́ òfin fun akẹ́kọ̀ọ́ tí a dárúkọ lókè yìí, pé Àjọsọ òkè yii yé mi, ati pé mo gbà, maa si tẹ̀lé gbogbo awọn ìlànà àti àgbékalẹ̀ rẹ̀ lórúkọ mi àti lórúkọ akẹ́kọ̀ọ́ náà.

| | |
|---|---|
| Ibọwọlu Obi: | Deeti: |

**ILANA BI A Ó TI ṢE É:** <u>*Ojulowo*</u>: Faili Ile-iwe/Akẹkọọ // <u>*Ẹdà:*</u> Akẹkọọ/Obí